# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 334 LAGOS SATURDAY AUGUST 25, — AUGUST 31 1962. KOBỌMEJI (2D)


TANI AGBA L()YA ?

# Oloye Akintola Fi Awolowo Jewo Ni Ile Iwadi Coker

OJỌ apara ati ẹrin ni ọjọ ijẹta jẹ ni iwaju awọn Igbimọ oluwadi ti o nṣe iwadi lori ọrọ ajọda iṣẹ mẹfa Ijọba ti Ipinlẹ Iwọ Orun ti nwọn nṣe ninu ile iwe-giga ( King's College ) l'Eko. Ninu nwọn nṣe ọrọ iwadi na lọwọ ni ọrọ kan ọrọ larin Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnitere ( A. G ) ati Oloye S. L. Akintọla, olori ẹgbẹ oṣelu tuntun (UPP) ti nwọn bẹrẹsi sọ oko ọkọ si ara wọn pẹlu apara akọ.

Ọgbẹni J. A. Ọdẹbiyi tiṣe Minisita alamojuto ẹ[illegible] Ijọba Ipinlẹ na ri ni o wa ninu apoti ẹlẹri ti Oloye Akintọla mbilere ọrọ lọwọ rẹ lọwọ, ti Oloye Awolọwọ fi dide ti o tako o lori iwe ti Akintọla gbe lọwọ ti o nwo ki o to bere ọrọ lọwọ ẹlẹri na.

Oloye Awolọwọ; Nko fẹ yọ lọya ọrẹ mi lẹnu, ṣugbọn a ko fi ori ọrọ iwe iranti awọn Igbimọ-nla ti sibi kan. Ti o ba jẹ wipe ninu ẹda iwe na ni o ti nka ọrọ ibere rẹ jade, o yẹ ki gbogbo wa ni ẹda iwe na lọwọ.

Oloye Akintọla: Ma mu u wa si ibi lọla, ṣugbọn mo jinna diẹ si lọya ọrẹ mi, iru wa bayi ti kọja ẹniti o le maṣe alami ẹtẹlẹmuyẹn.

( wo iyoku ni oju ewe kẹjọ )

ORO OLOTU:

## O Dori Aka'hin Akara Degungun

ODI ori aka-ehin akara di egungun ni ọrọ awọn olotu Ijọba Apapọse wa l'Eko pẹlu Oloye Hezekiah Ọladipọ Davies, ọkan ninu awọn ogunagbongbo lọya (lawyer) Nigeria ti gbogbo Ilu mọ orukọ adape rẹ ni HOD ti awọn Ijọba agbaiye (United Nations) pe wipe ki o jọwọ wa pẹlu awọn kan ti awọn yan wipe ki o wa ba awọn ṣe iwe eto ofin Ijọba ilu Congo gẹgẹbi ẹniti awọn mọ wipe o ni ẹkọ ijinlẹ ninu iru ọrọ bẹ.

Gbara ti Oloye Davies ti jẹ ọhẹn fun wọn tan wipe on a ṣe bẹ ni o si ti lọ sọ fun Gomina-agba ọlọla Dokita Azikiwe ati Alhaji Tafawa Balewa Alakoso Ijọba Ijọba Apapọse nipa ọrọ na, gbogbo wọn si kii ku orire. Oloye Davies si gba iwe aṣẹ lati mura lati ma lọ si Congo ki kọngọ to sọ ninu ile iṣẹ Minisita alamojuto ọrọ okere, Ọgbẹni Jaja Wachuku. Nwọn binu wipe o dabi ẹnipe lọya Davies fẹ gbe nkan kọja lẹhin awọn. Nwọn mu gegekalamu wọn, nwọn si fi ba ọrọ na jẹ lọdọ awọn ti nwọn yan lọya na sinu iṣẹ nla na.

( Wo yoku loju ewe kẹjọ )


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS,

LONDON OFFICE
15,THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell

Telephone London Wall 4303
Cable & Telegrams Natbaniger : London
Head Office Representative in London.
E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

# Awo Irawo

## E yi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Wa jẹ ẹnikan ninu awọn ti ko ni gbe inegbe lọwọ nipa ọrọ tukeradọ ti o ba bẹ silẹ sugbọn wa ṣe oluranlọwọ fun ti ko ni anfani bi tirẹ.
PISCES (Feb 21-Mar 20) Gẹgẹbi ọpọlọpọ enia iwọ na nà a se oni rere wa si lu awọn se ajọ pataki kan.
ARIES (Mar 21-April 20) Ki o ma se yà ẹ jẹun pupọ to to ba ti lar n ọsẹ. Wa ni anfani ati ṣe ise re yọri si rere.
TAURUS (April 21-May 20) Wa ni anfani lati jẹ ere ọja kan lọjọ Aje (Monday) ti mbọ yi.
GEMINI (May 21-June 21) Alejo kan yio ba ọ. Gbebo ọrẹ ti ni wa ti ṣe wahala lati yanju sì ọn.
CANCER (Jun 22-July 23) Ki o gbidanwo lati ṣe ohun ti awọn ti nkan ba jọ da iwọ nwọn pọ.
LEO (July 24-Aug 22) Irinajo dẹ wa fun ọ ninu ninu ose Owo a wọle fun ọ.
VIRGO (Aug 23-Sept 23) Olufẹ rẹ kan a wa ki ọ laarin ọsẹ yi. Ṣọra pelu awọn alajọsebo enia.
LIBRA (Sep 24-Oct 23) O ni lati ma sara pupọ, ki o ma ṣe ana pupọ, ki o mọ ṣe wọkọ ifaa.
SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ni opere ọsẹ yi ni nkan yio lọ kọkọrọ ẹni fun ọ, lẹhin rẹ gbogbo nkan a lọ dede.
SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) O fẹ, o kọ irawọ rẹ a tan imọle ẹre ninu ọsẹ yi.
CAPRISCORN (Dec 23-Jan 21) Awọn enia kan a fẹ rẹ ọjọ lọjọ Aje (Monday) ti mbọ yi ki o ṣọra pupọ.

## Iya Oni Ogogori Fi Owo Tanran

IBADAN—Ni ijẹrin ni Adajọ agba kotu awọn ọlọpa ni ki obinrin ọdaran kan ti o njẹ Marien Meye, eni ọdun marundinlogoji fi ponun marundinlogorin (£75) tanran fun panu garawa ọti ogogoro merinleladọta (54) ti awọn ọlọpa ri ko ninu iyara rẹ.

## Oro Ile Igbimo:

## Onifayawo Pade Agbako Lodo Okoti-Ebo

AWỌN baba oniṣẹ fayawọ pade agbako lọdọ Oloye Festus Okotie-Eboh, Minisita alamojuto owo ninu Ijọba Apapọṣe l'Eko, nitoripe nigbati nwọn bẹrẹsi ṣe ipade igbimọ ni ọsẹ ti o kọja, Oloye na gbe iwe ofin pataki kan wa siwaju Igbimọ na ninu eyiti o wipe on fẹ ki awọn igbimọ na fi aṣẹ sii, ki awọn akọwe ibode (Custom Officers) le ma mu ibọn lọwọ ti nwọn ba nṣe ọdẹ awọn oni-fayawọ lọ.

Oloye Okotie-Eboh ni ọpọlọpọ awọn akọwe Ibode ni awọn baba oniṣe fayawọ yi ti pa lẹnu iṣẹ wọn. O ni awọn oniṣẹ fayawọ ko ni anu lẹnu iṣẹ ti awọn nṣe.

Oloye yi ni ko niye awọn akọwe ti nwọn ti pa ni ọna Calabar ti nwọn ba nko ẹru wọn bọ lati Fernandopo. Awọn Igbimọ si ti fi ọwọ si ofin na, nwọn ni ki awọn akọwe 'bode ma gbe ibọn lọwọ nigbakugba ti nwọn ba nlọ ṣe iṣẹ nibiti o le. Awọn oniṣẹ fayawọ pade agbako.

### Aka'nia

Mallam Waziri Alhaji Ibrahim, ọkan ninu awọn Minisita Ijọba Apapọṣe ni on ti gbesẹle ariwo lere "kakaki" ti gbogbo awọn enia npa kiri lori iyọrisi enia kika ti nwọn nsọ wipe nwọn ti ṣe iwe rẹ tan, awọn ni ko gbe e jade. Alhaji Ibrahim sọ fun gbogbo awọn ti o wa ni ipade Igbimọ pe ato-oṣu melo kan si asiko ti a wa yi ki Ijọba to le gbe ikede iyọri enia-kika (census) na jade fun gbogbo ara aiye.

### Eja Nla

Orisirisi ẹja ni o mbẹ ninu ibu omi sugbọn nwọn ti gbe ofin kan jade ninu ipade Igbimọ Apapọṣe ti nwọn nṣe nisisiyi pe o loju ẹja ti o gbọdọ mu wọ ilu Nigeria. Nwọn ni ọpọlọpọ awọn ẹja miran ni ko yẹ rara lati mu wọ ilu yi. Nwọn pe ofin na ni Live Fish (Control of Importation). Ẹja-aye ti o ba mu wọlu o ni lati gba aṣẹ lọdọ awọn alaṣẹ Ijọba.



# Sardauna Pelu Awon Oga Soja

Aworan yi ni igbati Ọlọla Sardauna Sokoto lo si ilu Oyinbo ti o lo be awon omo ile Nigeria ti o ko ise soja wo ni ilu ti nwon npe ni Sandhurst.

Foju Sona Ni Ose ti o mbo yi omo Alahusa yio so tenu re.

OMO LISABI NI :

# Awa Egba Korira Ote

## Akoko Ko Wa Ogbon Odun Yi

Inu mi dun l a t i ri iwe ẹnyin Olotu w i p e ki nkọwe diẹ lori ọrọ ti o wa nilẹ, atipe ẹ o fi orukọ bo mi laṣiri. Mo dupẹ l ọ w ọ yin pupọ fun iyi ti ẹ fun mi wipe ki nkọ "wosika" yi, ṣ u g b ọ n ṣe ẹnyin na mọ wipe awa ọmọ Ẹgba eru kii ba wa. Ẹ fi orukọ bo mi l'aṣiri, ẹ ko fi orukọ bo mi ni aṣiri ko wipe ki nmọ sọ nkan ti o wa lọkan mi rara.

Awa Ẹgba kiṣe ọtẹ nitoipe ọ.: ntẹ enia ni. Awọn Yoruba npa owe wipe bi awọn enia kan ba nti inu oko-were bọ awọn kan a ṣẹṣẹ ma lọ. Emi ko fi owe yi ba ẹnikan wi, ọrọ ni o lọ bi owe.

Ni iwọn nkan bi adọta ọdun sẹhin awa Ẹgba inu ominira ni a wa, a si nṣe Ijọba tiwa eyi ti awọn Oloyinbo sọ ni Ẹgba United Goverment, Ijọba ilu Ẹgba ṣugbọn ede aiyede kan ni o bẹ silẹ ni 1914 ti nwọn pe ọtẹ igba na ni ogun Ijẹmọ. Eleyi jẹ ki awọn Gẹsi gba ominira wa lọwọ wa nitoripe nwọn ri pe boya a ko ni le mọọ lo.

Eyi kọ wa lọgbọn pupọ lọmọde lagba.

Ikeji ni ti ogun Adubi. Ninu nwọn gba ominira wa yi lọwọ wa, nwọn ko gba ni ọrọ owo-ori (tax) ba tun da nkan silẹ. Iyẹn ninu ọdun 1918, nwọn si pe ọtẹ igba na ni Ogun Adubi. Ẹniti ọrọ na ṣe oju rẹ ni o le sọ.

O yẹ ki gbogbo eyi kọ wa lọgbọn pe ko si nkan rere ninu ọtẹ ati rikisi ṣiṣe. Awọn Oyinbo alawọ funfun papa ti o wa k ọ w a ni ọna ti a fi ṣe ilu ti o ba o j u mu, ti o si tọ'na feran lati ma fi ọ g b ọ n ọlọgbọn kọ gbọn, nwọn a si ma ri ẹ k ọ ti o wulo ninu awọn nkanti o ti ṣẹlẹ si awọn ara atijọ ti nwọn ma npe ọrọ wọn n a ni

FACTS FROM HISTORY

Boya iya t i awa Ẹgba ọmọ Lisaba ti jẹ lorişirişi na ni o j ẹ k i nwọn ma yan wa ni'sẹ oṣelu nibikibi ti ọrọ ba dikoko. A si nma fi egungun otolo to.

### Ruke-rudo

Ọrọ rukerudo t i o b ẹ silẹ ni Ipinlẹ Iwọ O r u n nisisiyi t'ẹru tọmọ, tọmọde tagbe pẹlu onile ati olode ni ọrọ na ba wi, o yẹ ki a fi ọpọlọpọ s u r u yanju ọrọ na ti a k o b a fẹ ki iya ẹlẹmi mẹrin jẹ n w ọ n ọmọ wa ati awọn ọ m ọ ọmọ wa lẹhin ọla. K i a mọ ṣe ọrọ rukerudo na ni ọrọ awada, ki a mọ ṣeṣe e ni ọrọ Awẹ ni a bi mi, Akimọrin ni a ti w o mi dagba.

Awọn ẹlomiran, a w ọ n arijẹ ninu madaru, ti nwọn ba ti ri w i p e ede aiyede wa larin awọn oṣelu bayi inu wọn a ma dun aitoripe oko (cocoa) w ọ n ni o so yẹn, nwọn a si ri o w o gba nibẹ. Nwọn a mọ lọ gbọ t'eku sọ f'ẹyẹ; nwọn a si tun mọ gbe ọrọ ẹiyẹ lọ sọ f'eku.

Bi a ko ba pe ỌDỌFIN inu wa, ki a tun pe ARO inu wa, ki a f'ori kori, ki a mọ ọna ti a gbe ọrọ na gba, ẹni iwaju a d i ẹni ẹhin; ẹnịẹlẹni a g b o i ṣ e w a ṣ e.

Ọlọrun m a j ẹ k i ẹn ẹlẹni gba iṣe wa ṣe o. Ọr re o, gbogbo ẹ n y i n ọm Yoruba, Ẹgba ọmọ Lisab ki nyin o.

## Olye Olosi Ni Ilorin F'ada Kori

ILỌRIN—Nwọn ni a njẹ ẹkuru werewere wipe ki o le tete tan ninu awo, nibẹ na si ni awọn k a n tun ngbọn owọ ẹkuru na sinu awo ni ọrọ Ọba Ezekiel Afolayan, Ọba ilu Ọsi ni agbegbe Ilọrin ti awọn kan ninu awọn ara ilu rẹ ni awon yọ loye laipẹ yi.

Gẹgẹbi irohin ti o tẹ wa lọwọ, a gbọ wipe ede aiyede diẹ wa larin awọn Oṣelu Ọba yi pẹlu ẹwọn ọ m ọ ẹgbẹ Olomi (NPC) ti nwọn wa ninu Igbimọ ibilẹ ilu na, awọn kan ni ninu ẹgbẹ oṣelu ti o wa awọn ko mọ, awọn kan ni apa keji ni ko ṣe ti awọn; nwọn ni ko gbọran si awọn lẹnu.

Oni irohin Eleti-Ọfẹ n' nigbati on de Afin Ọba na on ko le ri i ṣugbọn ẹnikan ninu awọn ijoye ọmọlẹhin rẹ ni Ọba Fọlayan ko binu ẹru, ko si binu

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

YORUBA CHALLENGE

September-October 1962

O TI JADE FUN TITA.

Kọ awọn ọgbọn nipa:

Ohun ti afa Mọnamọna

ati

Bi a ti ṣe le bọ lọwọ sisan ara

Iwe oloju iwe 24 yi ko le'wo.

4d pere ni iwe kan.

# Isinku Yaya Dun L'Ebute-Metta

EBUTE-METTA—Ni ọjọ Eti (Friday) tiṣe ọjọ ketadinlogun oṣu yi ni Iyafin Marian Ọladunni Vincent, ẹniti gbogbo awọn ara Ebute-Metta mọ adape orukọ rẹ ni "YAYA" jalaisi ninu ile rẹ ni 99, Griffith Street l'Ebute-Metta. Gbara ti nwọn ti tu ọfọ rẹ na ni gbogbo awọn ọmọloku ati ẹbi ologbe na ti pe si bẹ, awọn bi Iyafin Caroline Oye Smith, Ester Adebisi George, Dorcas Adejoke Ogundeyi, Ọgbẹni Sam Adeyemi Vincent ati Jonathan Niyi Vincent.

Ni ọjọ Aje ni awọn gbe oku arabinrin na lọ si Ṣọṣi African Salem ni Agọ Ẹgba fun isin aṣe gbẹhin ki nwọn to gbe e lọ sin ni itẹ ni Agọ Ẹgba kanna. Gbogbo awọn ọmọ ọmọ oloku, awọn bi Sisy Joko Smith (auntie Apapa), Samu Ogundeyi Patrick Ogundeyi, Michael Ogundeyi, Babatunde Awe, Elizabeth Ogundeyi, Hezekiah Ogundeyi ati Kunbi Vincent ni nwọn nawo nara ni ibi oku iya wọn agba na.

Ọladunni, ọmọ ajo gbẹru majo gb'ẹkọ, eru ni sin ni, ẹkọ ko nsin enia. Ọmọ a fi ẹyẹle ke towo towo. Ọmọ owo gbele dẹfun, o digba ọrun re.

# ELETI–OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Koseko Street, Lagos. "ELETI OFE," LAGOS

P. O. Box 465 Phone 23370.

VOL XIV No. 834. SATURDAY AUGUST 25, - AUGUST 31


# Oke Mewa Ponun

AWON Yoruba a ma pa owe wipe A ṣẹṣẹ ti ẹsẹ kan bọ odo omi nwọ o lọ, iyẹn ni ọrọ awọn olotu Ijọba Apapọ (Federal Government) wa l'Eko ti nwọn da ẹgbẹ onisowo atewe kan silẹ ni Apapa ninu ọdun ti o koja, ti nwọn npe orukọ ẹgbẹ na ni Nigerian National Press, ti nwọn ntẹ iwe irohin meji, MORNING POST ati SUNDAY POST.

Irohin ti a gbọ nipa ile ibi iṣẹ na ko ba oju mu rara. Ṣugbọn awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ gẹgẹbi iṣẹ wa, ti a sọ fun nyin wipe agbọrandun gbogbo awọn ara ilu ni a jẹ ati pe a ko ni ṣe alai sọ gbogbo nkan ti o ba nlọ ni ilu fun nyin, ko ba ṣe rere ati buruku.

A gbọ wipe ni arin ọdun kan ti awọn ẹgbẹ onisowo atẹwe na bẹrẹ si ṣe iṣẹ, ọke mẹwa ponun (£200, 000) sarai ni nwọn na ladanu. Ọke mẹwa ponun ko mọ iṣẹ ọgọrọ owo. Owo gbogbo ilu ni.

## Kise Omode Owo

Nwọn ni bi a ko ba mọ ibiti a gbe nlọ a mọ ọna ibiti a gbe ti mbọ. Boya ẹnyin ara ilu ko niran ikilọ pataki kan ti awọn ṣe fun awọn Olotu Ijọba wa nigbati nwọn ngbero lati da ẹgbẹ onisowo itẹwọ na silẹ. Nwọn ni ki awọn mọ iṣẹ naa nitoripe owo awọn ara ilu ni nwọn fẹ da na sin. Nwọn kọ, nwọn se ẹ.

Awọn ti o le ṣe baba-elo fun ile iṣẹ na, nwọn ko fi ida asẹ le nwọn lowọ. Ọpọlọpọ awọn ti ko yẹ ni nwọn ko jọ sibẹ. A gbọ wipe bi o ba ti le fi aṣọ leka, ti o gba Ikoyi lọ, ti o si ti fi ara ninu awọn Minisita wa, o ti di Alaba-iṣẹ nyen. Ko si ọrọ wipe o mọ iṣẹ nibẹ.

Ki a sọ otito fun ẹyin ara ilu. Ijọba kan kiṣe iṣẹ owo iwe titẹ. Ijọba ti o ba ṣe e ki ẹ mọ wipe akaba tikisi ni nwọn gun nibẹ.

Gẹgẹ bi a ti wi ṣaju ti a ko paro, ni ijarun ni Ọgbẹni H. Colsover, ngangan ibi iṣẹ na, ti o binu ju ipo alamojuto ile iṣẹ na silẹ losẹ ti o koja, se alaye fun awọn oniwe irohin wipe ILE RIKẸ NI ILE itẹwe "Morning Post" ni Apapa. Otọ ni nkan ti nwọn yio sọ ni owuro, oto ni omiran ti yio fun jade lati Ikoyi lẹrin. Eyi ara.

Nigbati yio ba to iwoyi ọdun ti mbọ, ẹ gbọ iyẹ ọmọ ti iṣẹ iwe titẹ ni Apapa yio ti tun bi ni gbese asan-santan.

Ọrọ re o, ẹnyin ara wa!

## Iwe Si Olotu

# Mo Fara Mo Oro Omo Obanta

EJỌWỌ, Olotu, ẹ gba mi laye ninu iwe irohin Eleti Ọfẹ nyin lati kin Ọmọ Obanta lehin fun ọrọ ti o sọ sinu iwe na ni ọsẹ ti o koja.

Otitọ ọrọ bi isọkusọ lori, awa Ijẹbu feran tẹmbẹlẹkun. Ko si ilu ti abosi ko si sugbọn ti ọdọwọn o peleke.

Boya bi oniwe nyin ati awọn miran ti nfi ọrọ na ṣe iwasu fun wa yi, a le ronu ki a pa iwa wa da, ki a wa ọna ti a o ma fi ṣe nkan rere sinu ilu ju ọna abosi lọ.

O ya mi lẹnu wipe ọkan ninu awa ọmọ Ijẹbu na ni o dide ti o daba ninu ile Igbimọ l'Eko wipe ki nwọn da Ijọba Ipinlẹ Iwọ orun si ọna meji (Mid-West).

Nitotọ ọmọ ale ni fi ọwọ osi juwe ile baba rẹ. Emi faramọ ọrọ otitọ ti ọmọ ọbanta sọ.

Mo dupẹ lọwọ nyin fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
J. Adenaike,
Ijẹbu-Ode

## Awon Ara Ghana

KILOṢE ti awọn Aganyia (Ghana) ko le ṣe ikilọ fun awọn Olotu Ijọba wọn wipe ọna ti nwọn tọ ko dara? Lemọ femọ wọn pọ pupọ ju lori nkan ti ko yẹ ki awọn fun ika mọ.

Ko si ẹniti yio gbọ irohin wipe nwọn le ojiṣe Ọlọrun kan kuro nilu ti ko ni ya a lẹnu, ti ko ni ṣe ni kayefi.

Kinni ọṣẹ ti Alufa ojiṣe Ọlọrun yi ṣe? O ṣe ikilọ ninu iwasu re fun awọn ara ilu nipa ẹgbẹ buruku ti nwọn fi awọn ọmọde kekere wọ, atipe nwọn ko nkọ nwọn ni iberu Ọlọrun nibẹ.

Eyi ko to ija rara, ko si to nkan ti a le le ni wipe ki a jade nilu si. Bi a ba ri wipe nkan ti a nkọ awọn ọmọ wa na tọna, ki a fi Alufa silẹ ki o mọ sọ nkan ti Ọlọrun ran.

Emi ni,
Yaba. Eman Adedigba.


HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kavachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose ... today order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England



E Ma ka Iwe Irohin Eleti-Ofe
Fun Irohin Aladun
Ki E si ma polowo Oja yin Losose.


Oloye Ilorin Kan Fada Kori, wo oju ewe keta

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI OWỌ AYILUKA)

## Eru Tan Nle

O dun mi pupọ ti ọrẹ mi Dokita Michael Okpara, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ko le mu mi lọwọ lọ si ilu Oyinbo ti o nlọ ni ọtẹ yi. Mo gbọ wipe awọn ti yio ya wọn ni owo ni o nwa lọ si ilu Oyinbo na. Bi ko ba tilẹ le mu emi lọwọ ṣe ko ba mu Sammy lọwọ; Dokita Aluko, "baalẹ e-ṣọ owo-na ti mu ile-giga julọ ni Ibadan ni mo wi yẹn o.

Mo ṣe iranti ọrọ ọmọ iya ti "baalẹ e jọwọ, ẹ-ṣọ-owo-na" yi sọ fun gbogbo awọn Alakoso Ijọba wa jake jado. O ni bi nwọn ti ṣe nnawo wa ko dara rara, o ni gbogbo ẹru ni o ntan nilẹ.

Ẹ tilẹ wa gbọ na, lọjọ melo ni ao ye ma ba wọn ja ajagba ti awọn olowo-ele (money lender) npe ni "maje-ki-a-ja" kiri? Oni a wa awọn ti yio tan wa lọwọ lọ si ilu Jamani, ọla o di ilu Jepani, ọtunla Amerika. Ọjọ melo ni a o ṣe eyi gba?

## Eyi Enmo

Ninu a nkegbe ko s'owo ko s'owo yi Dokita Adekoye Majekodunmi, Adele Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun tun fi ẹgbẹrin p ọ n u n ( £1,000 ) ra ẹrọ asọrọ-mọ-gbesi (radio) sinu mọto ayọkẹlẹ awọn ọmọ-lẹhin rẹ ti nwọn ndele de awọn Minisita Ipinlẹ na.

Mo gbọ pe o ṣe eyi ki nwọn le mọ gbọ ọrọ ti nwọn ba nsọ nipa wọn nibikibi ni. K o b u r u, nitotọ, eniti o ba ṣe nibi pẹpẹ ni jẹun nibi pẹpẹ. Ẹ niran ọrọ Dokita Aluko o, o ni ki ẹ r ọ r a n a owo yi nitori awọn ti mbọ lẹhinwa ọla.

Bi ọrọ Aluko ko ba ṣe lowurọ a ṣẹ lalẹ. Aluko Bangadeji, Bi a ko ba lobinrin nile a ki fẹ l'ooyọ, bi a ba fẹ ooyọ w a si ile, ẹran n i bani jẹ ẹ, mo gbadun rẹ o. Ẹ si ku abọ irin ajo ti Amẹrika ti ẹ de laipẹ yi. Ki ẹ ba mi ki Joyce ati awọn ara ile patapata.

## Ile Adura

Mo gbọ wipe Ogbeni wa Dokita Kwami Nkurumah fẹ da ijọ Ṣọṣi tirẹ silẹ lẹhin ti o ti le Alufa oyinbo Ọlọrun kan kuro nilu. Orukọ ti yio sọ ijọ tirẹ ni ko ti ye mi. Mo gbọ wipe ti nwọn ba ti da ijọ Ṣọṣi na silẹ Dokita Nkrumah ni yio ṣe Alufa-agba (bishop) on na ni yio si ṣe akapo owo ti nwọn ba nda ninu ile isin na. Ọjọ Satide ni nwọn yio fi ṣe ọjọ ijọsin ati pe ofin metala ni yio jẹ ofin isin wọn dipo ofin mẹwa ti inu Bibeli.

Eleyi na ko buru pupọ ju, ṣugbọn kini awọn Alufa Ṣọṣi na yi o mọ fi ṣe iwasu? Ede Ga ni tabi Twi?

## Rikisi Pin

Mo ba ọrẹ mi Oloye Ade Fashanu yọ fun ipo Ọga agba ti nwọn tun fun nibi iṣe re ni Apapa. Bi pari ẹran-ko ko ba fọ, ẹrẹkẹ ọmọ araiye ko ni kun fofọ rara. Mo ro wipe bi Oloye Fashanu ti gori aga yi a pana awọn onirikiṣi ti nwọn wa ni ibi iṣẹ National Press l'Apapa.

Mo fi Lisabi bẹ Oloye Fashanu, ki o ṣe ikilọ fun awọn ti o nfi oganjọ oru lọ pari ọrọ awọn ọga wọn lọdọ awọn Minisita ni Ikoyi. Ki a mọ ṣe ọrọ na ni pasan ti a fi na iyale ti o mbẹ laja fun iyawo.

## Kosoko Oba

Oloye Aminu Kọṣọkọ, ko gba gbẹrẹ rara, a r ọ ni loye, a du ni loye, awọn ẹbi Oloye yi d u r o ti i gidigidi. Moronfolu okun oye, Ajinibi ọga ogun, o duro nita Alasa ile, Alasa ile ko gbọdọ lọ s'oko, ko gbọdọ lọ s'odo. Ọmọ Olowu-Owu-a-wuna-pe. Ayiluka mbẹ lẹhin rẹ.

Mo ni ki a mọ ṣe ọrọ na ni ọrọ ọtẹ, ki a ṣe ni ebẹ ni a mbẹ osika. Ki a mọ jẹ ki awọn osika tẹ e ki a mọ wo wọn. Nitotọ bi enia ko ba lọkan gidigidi ko le ba wọn ṣe aiye oda oni. Oṣi a pa a, ọla a bu u lẹsẹ ni gbogbo wa mba kakiri.

Ki ẹ ba mi ki Oloye Ogunlana, Ọbanikoro ati awọn baba wa yoku.



# Oko Aje

**Ọlọla Prince Philip, oko Ọba ilu Oyinbo ni e nwo ninu aworan yi pelu awon emewa re ninu oko won kan ti nwon npe ni Bloodhound ti nwon fe fi ba won sare idije ni ilu Oyinbo ni ilu kan ti nwon npe ni Cowes. Ọlọla Philip yi ni yio wa oko-aje na. Eleyi kise akoko ti yio ba nwon fi oko dije.**

## Oloye Ołosi Ni Ilorin F'ada Kori

(O bere loja ewe kẹta)

ọmọ, ko si mu oṣelu kankan lọta. O ni gbogbo awọn oṣelu ilu on ọmọ on ni on mọ wọn si.

Ọba na si ti da esi iwe ti nwọn kọ si i wipe awọn da duro pada. Ninu esi iwe adapada na, Ọba yi ni ko ye on rara nkan ti on se ti nwọn fi fe ro on loye nitoripe on ko se nkan buruku fun awọn ara ilu on rara; o ni bi nwọn ba tile gba ida-aṣẹ ko nṣe wipe on ni o yẹ ki nwọn lo o fun.

Ọba na si ti fi ẹda iwe rẹ sọwọ si Minisita Alamojuto ọrọ awọn Oloye ni Kaduna, o tun fi ikan ranṣẹ si Ajẹlẹ Ilorin ati Alamojuto eto Ofin pẹlu Idajọ ododo ni Ipinlẹ Ariwa.

**Ka Irohin Ayiluka loju ewe karun**

# Faari Jade Laiye

Lemulọlọyi ni Ọgbẹni Ishọlọ Faari, ẹni ọdun mẹt'eladorin (73years) jalaisi ninu ile re, 17 Adam St, Okepopo l'Eko. Lemọmu Agba Ijọ Alatukeruni ni o si ṣe isin ikẹhin fun un. Awọn enia jankan-jankan pọ pupọ ni ibi aṣeye isinku na.

Awọn ọmọ oku na awọn bi Olori Amadatulai Awẹlẹwa Ashabi Adagun, Shewu Tijani Faari, Habibulai Faari, Falilatu Faari, Laolat Faari na wahi-wọ li owo

Ana o k u na, Iyaafin Sabitiyu Ọmoyay, Adufẹ Adagun l'ọmọyọ ni ibi aṣeye isinku na. O roṣọ dẹdẹ o si gbayi. Ẹsọ asiko ni o ṣe

Enia gidi, gbajumọ, alafẹ, ọloyaya ati olufọkansin (musulumi ododo) ni oloọbe na ni igba aiye re, o si fẹran lati ma a pari ija ti o ba sẹlẹ larin awọn ẹbi ati ijọ (jamma) rẹ ni adugbo,

Awọn ẹbi Alhaji Y. A. Disu (Awaiyewaṣere) ko ida kan ni ibi aṣeyẹ isinku na.

Ki Oluwa gbee si afẹfẹ ire.

**DAGENITE**
BATTERIES
*give you a longer run for your money!*




Sole Agents & Distributors for Nigeria
**LEVENTIS MOTORS LTD.**
Lagos, Apapa, Ibadan, Kaduna, Kano, Jos, Port-Harcourt, Aba

# Ile Titun Fun Awon Elepo



LAGOS-Laipẹ yi ni Ọgbẹni Maitama Sule, Minisita alamojuto nkan isura inu ilẹ fi ọwọ si iwe adehun kan loruko Ijọba Apapọṣe pẹlu awọn Oyinbo onise epo moto ti nwọn nwa epo nilẹ kakiri ti nwọn npe oruko ibi iṣẹ wọn na ni BP-Shell Petroleum Refining Company of Nigeria Ltd lẹhin ọdun meji ti nwọn ti nfa ọrọ adehun na nipa ile iṣẹ epo moto ti nwọn fẹ kọ si Alesa-Eleme nibiti nwọn yio gbe ti m a p ọ n epo-mọto.

Ọdunrun ẹka (ac.e) ilẹ ni awọn oniṣẹ epo-moto na gba ti nwọn yio kọle na si, owo gọbọyi (£8million) ni nwọn yio na si ibi kikọ ile iṣẹ na. Nwọn n ẹgbaa ('00) oṣiṣẹ ni awọn yio gba si ibi kikọ ile na.

Aworan ti ẹ nwo n i a p a osi yi ni bi ibi iṣẹ na yio tiri bi ilu tuntun ti nwọn ba kọ tan.

**Ka Irohin Ọmo Lisabi Ni Loju ewe Keta**

# Farming Tractors To Be Produced In Morocco

COVENTRY An Agreement for the assembly and progressive manufacture of Massey-Ferguson Tractors under licence has been concluded with the Moroccan authorities. The anticipated annual output will be of the order of eight hundred to one thousand Tractor Units.

Detailed production plans were discussed by Mr. John Beith, Director Special Operations, when, accompanied by other senior company officials, he conferred last week in Rabat with Mr. Mehdi Abdeljeleil, Secretary General of the Ministry of Economy and General Manager of BEPI, the Industrial Study Bureau and Mr. Omar Benchequoun; also of BEPI.

Mr. Beith said that the Company's equipment had been sold in Morocco since the turn of the century and had always enjoyed favourable acceptance by farmers there. He added that his Company was pleased that thisagreement would provide the opportunity to maintain and extend this good relationship.

Massey-Ferguson is the world's largest manufacturer of Tractors, Combines and Diesel Engines.

## Nigerians Pass Out From Hendon Police Course

LONDON—Two Nigerians were among 22 Overseas police officers who were congratulated on their "very high standard" at a passing-out parade at the Metropolitan Police Training School at Hendon, near London, this week.

Sub-Inspector M. Dikwa from Sokoto, and Sub-Inspector J. Ohale from Owerri have just completed a 20-week course covering all aspects of police work under the supervision of Mr. R. W. Lavrick who spent 23 years with the Nigeria Police, retiring four years ago as Assistant Commissioner.

Addressing the Parade, Mr. C. H. Fenner, Commissioner of the Royal Federation of Malaya Police, said: "This high standard you have attained reflects not only upon yourselves but upon the guidance and assistance you have received from the Commandant and his staff here. Police forces overseas who send officers to these courses hold them in very high regard."

Over 600 policemen from all over the world have been trained at the 26 special courses for overseas police officers held at Hendon over the past 11 years.

## Sir Winston Churchill Returns Home

LONDON - Sir Winston Churchill left the Middlesex Hospital yesterday and was driven by ambulance to his London home in Hyde Park Gate. With a broad smile, his famous wartime victory sign, and a big cigar in his hand, he waved in response to cheers from the crowds outside the hospital.

The famous elder statesman and former Prime Minister was taken to the hospital 55 days ago, on 29th June, after being flown from Nice in a Royal Air Force ambulance Comet. The previous day he had fallen in his Monte Carlo hotelbedroom and fractured his left thigh.

Mr. Philip H. Newman, the surgeon who performed the operation on Sir Winston's leg was among those who waved farewell to him as he was driven home.

## Two Nigerians Films For Festival

LONDON—Two Nigerian films have won the distinction of being chosen for showing at this year's international film festival at Edinburgh, whose organisers select what they consider "the best feature and documentary films made each year in all parts of the world".

"We are delighted to see films from Nigeria," the festival's publicity officer Mr. James Crawford told a correspondent.

"Competition from all over the world is always strong and we can show only a small proportion of films offered," he added.

Advt. NO. 134

## NOTICE

### NIGERIAN HONOURS, DECORATIONS AND AWARDS

The National Committee on the award of Nigerian Honours would welcome suggestions from the general public on the following questions :-

(i) Do you consider that there should be only one set of National Awards, or do you consider that there should ALSO be Regional Awards either for services rendered to the Regions or in recognition of visiting foreign dignitaries ?

(ii) Do you consider that such awards should take form of :-

(a) titles, which qualify recipients to use letters after their names, or

(b) decorations, which qualify recipients to wear medals on ceremonial occasions, or

(c) both, or

(d) neither ?

(iii) Do you consider that Foreign Honours should be accepted by Nigerians, with or without the approval of the Federal Government ?

2. Please address all communications to :-

The Secretary
National Committee on Nigerian Honours,
c/o Cabinet Office,
LAGOS.

3. It will be appreciated if your suggestions are forwarded to the Secretary not later than the 30th of September, 1962

ORO ILE IGBIMO:

# Kele Gbe Baba Onijangbon Ti O Ba Ja Ninu Ile Igbimo

KADUNA—Ni ana ni gbogbo awọn ọmọ ile Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa fi ọwọ si ofin tuntun kan ti Ọlọla Amadu Bello, Sardauna Sokoto tiṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ na gbe wa si iwaju Igbimọ na. Ofin na fun Alaga Igbimọ na ni agbara lati fi kele'gbe ẹnikẹni, ko ba se ọmọ ile Igbimọ tabi alejo ti o wa wo iran ni, ti o ba da Ijangbọn silẹ ninu ile Igbimọ nigbati nwọn ba nṣe ipade lọwọ, ki nwọn ti i mọle, ki nwọn si fi iya ti gbogbo Igbimọ ba ri pe o tọ si oluwa rẹ jẹ.

Nigbati nwọn bẹrẹsi sọrọ alaye lori ofin tuntun na Alakoso Ijọba Ipinlẹ na Sardauna ni awọn ti ṣẹ iru ofin bẹ ri ni iwọn ọdun mẹjọ sẹhin sugbọn agbara ti o wa ninu ofin ti atijọ yẹn ko to rara nitoripe bi ilẹ ti nmọ ni awọn ọmọita npọ si. Eyiti nwọn ṣe ninu ile Igbimọ Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ibadan ni iwọn oṣu kẹrin sẹhin, ti ọkan ninu ọmọ ile Igbimọ na bẹrẹsi fo sori aga bi ọbọ lagido, ti o da rukerudo silẹ, ti kọ awọn lọgbọn. Awọn ko si ni fẹ ki iru ọrọ bẹ ṣẹlẹ ni Ipinlẹ awọn nibi rara.

Lọna keji, Ofin na tun da abo bo awọn ọmọ ile Igbimọ na nipa ọrọkọrọ ti nwọn ba sọ ninu ajọ Igbimọ, ko ba ṣe ọrọ lori ọrọẹbẹ (petition), aba lori ofin tabi ọrọ bẹbẹ nipa nkan ti o nlọ larin ilu, ko si ẹniti o gbọdọ pe wọn lẹjọ si Kotu lori ọrọ na rara.

## Ipinle Tuntun

Ọgbẹni Vincent Orjime, ọmọ ẹgbẹ Afẹnfẹre ti (AG) o wa ninu ile Igbimọ na ni awọn faramọ Ofin tuntun na nitoripe iru ofin bẹ a ka awọn oniwa buruku lọwọ ko lati wa da eto Ijọba ru ninu ile awọn aṣofin.

Ṣugbọn Ọgbẹni Ọlarewaju Afọlayan tiṣe aṣoju ọmọ Ẹgbẹ Olomi (NPC) lati Ilọrin nio yẹ ki awọn tẹ ọrọ na mọ gbogbo apejọ leti wipe anfani ti o mbẹ ninu ofin tuntun na ko nṣe nkan ti awọn le fi gbo ilẹ rara. Ti o ba jẹ wipe iru eto ofin bayi ti wa ninu ile Igbimọ ni Ibadan ni ọrọ wọn ko ni ri bi o ti ri lọjọ oni.

Nipa ọrọ Ipinlẹ tuntun (Mid-West) miran ti nwọn ngbero lati da silẹ ni Iwọ Orun, Sardauna ni o yẹ ki awọn fọwọ si ọrọ lati da Ipinlẹ tuntun na silẹ, ki awọn le fun awọn ara ilu na laye boya awọn na fẹ tabi nwọn ko fẹ ki nwọn da a silẹ. Ọlọla Amadu ni Alatiṣe ni mọ atiṣe ara rẹ; gbogbo ọrọ lati da Ipinlẹ tuntun na silẹ wa lọwọ ara Mid-West.

Larin iṣẹju akan gbogbo ijoko ile Igbimọ na si ti fi ọwọ si pe ki nwọn da silẹ.

Ni ọsẹ ti mbọ ALHERI ọmọ HAUSA yio sọ ọrọ ẹnu rẹ nipa rukerudo ti o nlọ ni Nigeria nisisiyi Wo oju ewe kẹta (3) fun nkan ti ọmọ LISABI ri wi.

ỌRỌ OLOTU

## O Dori Aka'hin Akara Degungun

( O bẹrẹ loju ewe kini )

Nitotọ tani ko mọ wipe o yẹ ki a fori fun awọn ti o ba wa lori aga ti awọn Hausa npe ni MAI—IKO. Sugbọn nkankan ni o wa ba ọrọ alaye ti Ijọba Apapọṣe ṣe lori ọrọ na jẹ, iyẹn ni wipe Dokita Elias ti awọn yan dipo lọya Davies ti ba wọn ṣe irufẹ iṣẹ bẹ ni Congo nigbakan ri pẹlu awọn enia mẹfa kan.

Awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ko ni ikunsinu rara nipa yiyan ti nwọn yan Dokita Elias dipo lọya Davies lati lọ si Congo fun iṣẹ nla na; a bọ ike lọwọ ọtun a fi si ọwọ osi, lọwọ lọwọ na si ni ike si wa. Sugbọn a gb'orun ọtẹ ati tẹmbẹlẹkun ninu gbogbo alaye ọrọ na.

Ni ọna kinni, ẹniti awọn alakoso Ijọba Agbaiye (United Nations) fẹ lati pe ki o wa ba awọn tun ori ilu Congo ti o dabi eyi ti o fẹ bajẹ se ni nwọn pe yẹn; ni ọna keji ẹwẹ, a ko gbọ irohin wipe nwọn pe ọkan ninu gbogbo awọn ti nwọn kọ yan sinu iṣẹ na wipe ki o tun wa ba wọn ṣe eto iwe ofin na, a fi awọn olotu Ijọba ti wa ni Nigeria. Nwọn ti gbagbe patapata wipe awọn ti o pe wọn si iru iṣẹ bẹ mọ agbara ati ẹtọ olukuluku ki nwọn to fi ọrọ iṣẹ na lọ wọn.

O ti lẹ yẹ ki inu wa ma dun gẹgẹbi orilẹ ede ti a ba ngbọ wipe nwọn yan awọn ọmọ wa ti o jinlẹ ninu ẹkọ si iru ipo bayi lati ilu okere, ki a maṣe mọ fi ọtẹ bọ ọ, ki a si mọ di wọn lọwọ lati lọ.

Ẹtẹ Awo ni ẹtẹ ọgbẹri.

## Oloye Akintola ati Awolowo

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Oloye Awolọwọ: Mo gbọ ti lọya ọrẹ mi nsọrọ nipa a nṣe alami ọtẹlẹmuyẹn. Iyẹn fi han gbangba wipe ko ti pẹ pupọ ninu iṣẹ lọya ṣiṣe. Bi o ba ti pẹ ninu iṣẹ na ni, a mọ wipe ko si lọya kan ti ko nṣe alami. Iṣẹ alami ni iṣẹ lọya.

Oloye Akintọla wa dide o wa dahun wipe Ṣe lọya ọrẹ mi ni emi ko ti pẹ ninu iṣẹ lọya ṣiṣe ni, o dara mo juba Ogboni-agba (Methuselah) ninu iṣẹ lọya. Sugbọn mo fẹ ki o mọ wipe awọn kan siwaju on na ninu iṣẹ lọya ṣiṣe. Eleyi mu ki gbogbo awọn ti o wa ni ibi iwadi na bu sẹrin, nwọn si rin in ni arin kara.

## Oro Doju e

Ẹniti o tun fa ọrọ ki ninu ipade iwadi na ni Lọya (Oloye) O. B. Akin-Olugbade ẹniti o ti fi igbakan ṣe Alaga Igbimọ Ayanilowo ri ni Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ibadan ti Dokita Majẹkodunmi ti fi igbakan fi si ihamọ apapandodo ri ki o to ba awọn ọmọ le Igbimọ aṣofin lọ si ilu Oyinbo.

Nigbati Oloye Akin-Olugbade yọ siwaju awọn oluwadi na ni ijẹta, o ni on ko fi tẹdun ọkan wa sibẹ nitoripe iwe ofin ti nwọn fi gbe ọrọ iwadi na jade ko tọna rara nitoripe awọn Olotu Ijọba Apapọṣe kọ lo ni ẹtọ lati pasẹ wipe ki nwọn ṣe iwadi na. O ni ju gbogbo rẹ lọ on tile ti pe Ijọba Apapọṣe na lẹjọ si Kotu-nla fun iwe ofin ti nwọn ha on fua ihamọle, nwọn ko si ti gbọ ẹjọ na.

Nitorina on fẹ ki Alaga Dokita Coker, mọ wipe iduro ẹniti-ọrọ-ndun ni on duro nibi ọrọ iwadi na, on ni on yio si ṣe agbẹjọro ara on. Dokita Coker ni on fara mọ ọ.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370; EDITOR (OLOTU): OLA. ONATADE
15, Kosoko St., Lagos,